6. Oun ni ẹni ti o kọ̀ ìtẹ́ rẹ̀ ninu awọn ọ̀run, ti o si fi ìpílẹ̀ rẹ̀ sọlẹ̀ ni ilẹ ayé; ẹni ti o pe awọn omi òkun, ti o si tu wọn jade si ori ilẹ̀ ayé: Oluwa ni orukọ rẹ̀. (Psm 104:3; Amos 5:8.)
7. "Ẹ̀yin kò ha dabi awọn ọmọ Etiopia si mi, Ẹyin ọmọ Israẹli?" ni Oluwa wi. "Emi kò ha ti mu Israẹli gòkè jade wá lati ilẹ̀ Egipti? Ati awọn Filistini lati ilẹ Kaftori, ati awọn ara Siria lati Kiri. (Isa 43:3; Amos 2:10; 3:1; Deut 2:23; Jer 47:4; Amos 1:5.)
8. Kiyesi i, oju Oluwa Ọlọrun nbẹ lara ilẹ ọba ti o kún fun ẹ̀ṣẹ̀, emi o si pa a run kuro lori ilẹ̀; ṣugbọn emi ki yoo pa ile Jakọbu run tán patapata, ni Oluwa wi. (Jer 44:27; ẹsẹ 4,10; Jer 30:11; Joel 2:32.)
9. "Wo o, nitori emi o paṣẹ, emi o si mi ile Israẹli ninu awọn orilẹ-ede, bi a ti nmi asẹ́ ti a fi nsẹ́ nkan, ṣugbọn horo kinkinni ki yoo bo sori ile. (Isa 30:28.)
10. Gbogbo awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ ninu eniyan mi yoo ti ipa idà kú, ti nwi pe, 'Ibi naa ki yoo lé wa bá, bẹẹ ni ki yoo ba wa lojiji.' (Amos 8:14; 6:3.)

**Imupada ijọba Dafidi lọ́tun.**

11. Ni ọjọ naa ni emi o gbe àgọ́ Dafidi ti o ṣubu ró, emi o si tun ẹ̀ka rẹ̀ ṣe; emi o si gbe ahoro rẹ̀ soke, emi o si kọ ọ bi ti ọjọ igbani: (A.A. 15:16,17; Psm 80:12; Isa 63:11; Jer 46:26.)
12. Ki wọ́n le ni iyoku Edomu ni ìní, ati ti gbogbo awọn keferi, ti a pe nipa orukọ mi," ni Oluwa ti o nṣe èyí wi. (Obad 19; Isa 11:14; 43:7.)

**Mimu ilẹ bọ̀ sipo lati maa mu irúgbìn jade.**

13. "Kiyesi i, ọjọ naa de," ni Oluwa wi, ti ẹni ti ntulẹ̀ yoo lé ẹni ti nkórè bá, ati ẹni ti o ntẹ̀ èso ajara yoo le ẹni ti o nfunrugbin ba; awọn òkè-nlá yoo si kán ọti-waini didun silẹ, gbogbo òkè kékèké yoo si di yíyọ́. (Lef 26:5; Joel 3:18.)

**Ìlérí ibukun fun Israẹli.**

14. Emi o si tún mu igbekun Israẹli eniyan mi pada bọ̀, wọn o si kọ́ awọn ahoro ìlú naa, wọn o si maa gbe inú wọn; wọn o si gbin ọgbà-ajara, wọn o si mu ọti-waini wọn; wọn o ṣe ọgbà pẹlu, wọn o si jẹ èso inu wọn. (Isa 60:4; Jer 30:18; Isa 61:4; Esk 36:35; 28:26.)
15. Emi o si gbìn wọ́n si orí ilẹ̀ wọn, a ki yoo si fà wọ́n tu mọ́ kúrò nínú ilẹ wọn, ti mo ti fi fun wọn," ni Oluwa Ọlọrun rẹ wi. (Jer 24:6; 31:28; Isa 60:21; Jer 32:41; Esk 34:28.)

31

# OBADIAH

**(B.C. 587)**

## ORI 1.

**Asọtẹlẹ nipa ìṣubú Edomu.**

IRAN ti Ọbadiah. Bayìí ni Oluwa Ọlọrun wí ni ti Edomu; Awa ti gbọ́ ìhìn kan lati ọdọ Oluwa wá, a si ti ran ikọ̀ kan si aarin awọn keferi, "Ẹ dide, ẹ si jẹ ki a dide ogun si i." (Isa 34:5; Esk 25:12; Joel 3:19; Jer 49:14; Isa 30:4; Jer 6:4,5.)
2. Kiyesi i, mo ti sọ ìwọ di kékeré laarin awọn Keferi: ìwọ di gígàn lọpọlọpọ.
3. Igberaga ayé rẹ ti tàn ọ́ jẹ, iwọ ti ńgbe inu pàlàpálá àpáta, ibugbe ẹni ti o ga; ti o nwi ni ọkàn rẹ̀ pe, "Tani yoo mu mi sọkalẹ?" (Isa 16:6; Jer 49:16; 2 A.Ọba 14:7; Isa 14:13–15; Ifh 18:7.)
4. Bi iwọ tilẹ gbé ara rẹ ga bi ìdì, ati bi iwọ tilẹ̀ té ìtẹ́ rẹ saarin awọn ìràwọ̀,

lati ibẹ ni emi o ti sọ̀ ọ́ kalẹ̀, ni Oluwa wi. (Job 20:6; Hab 2:9; Isa 14:13 –15.)

**Iparun Edomu ni a gbọdọ mu ṣẹ patapata.**

5. Bí awọn olè tọ ọ wá, ati awọn ọlọṣa ni òru, (bawo ni a ba ti pa ọ run!) wọn ki yoo ha jalè titi wọn yoo fi ní tó? Tabi awọn àká-èso-àjàrà ba ni o tọ̀ ọ wá, wọn ki yoo ha fi eso diẹ silẹ̀? (Jer 49:9; ẹsẹ 9,10; Isa 17:6.)

6. Báwo ni a ti ṣe ṣe àwárí awọn nkan Esau! Báwó ni a ti ṣe wá awọn ohun ikọ̀kọ̀ rẹ̀ jádé! (Jer 49:10.)

7. Gbogbo awọn ẹni ìmùlẹ̀ rẹ ti tì ọ jadẹ dé òpin ilẹ̀ rẹ: awọn ti wọn ti wa ni alaafia pẹlu rẹ ti tàn ọ jẹ, wọn si borí rẹ; awọn ti o njẹ ounje rẹ ti dẹ tàkúté si abẹ́ rẹ: kò sì sí ẹni ti o ni òye rẹ̀. (Jer 30:14; 38:22; Psm 41:9; Jer 49:7.)

8. Oluwa wi pé, ni ọjọ́ naa kọ́ ni emi o run awọn ọlọgbọn kuro ni Edomu, ati ìmòye kuro ni òkè Esau? (Job 5:12; Isa 29:14.)

9. Awọn alagbara rẹ yoo si bẹ̀rù, iwọ Temani, nitori ki a le ge olukuluku ti orí òkè Esau kuro nitori ìpànìyàn. (Jer 49:22; Amos 1:12; Hab 3:3; ẹsẹ 5.)

**Ẹ̀ṣẹ̀ Edomu wà ni ìhohò.**

10. Nitori iwa-ipa rẹ sí Jakọbu arakunrin rẹ ìtìjú yoo bo ọ, a o si ge ọ kuro titi lae. (Psm 137:7; Joel 3:19; Amos 1:11.)

11. Ni ọjọ ti iwọ duro ni apa keji, ni ọjọ ti awọn alejo kó awọn ogun rẹ ni igbèkùn lọ, ti awọn àjèjì si wọ inu ibode rẹ, ti wọn si ṣẹ gègé lori Jerusalẹmu, àní iwọ wà bi ọkan ninu wọn. (Psm 137:7; Joel 3:3; Nah 3:10.)

12. Ṣugbọn iwọ kì iba ti ṣíjú wo ọjọ arakunrin rẹ ni ọjọ ti oun di àjèjì; bẹẹ ni iwọ kì iba ti yọ̀ lori awọn ọmọ Juda ni ọjọ ìparun wọn; bẹẹ ni iwọ kì iba ti sọ̀rọ̀ irera ni ọjọ́ wahala. (Mika 4:11; Esk 35:15; 36:5; Psm 31:18.)

13. Iwọ kì ibá tí wọ inu ibode awọn ẹniyan mi lọ ni ọjọ ìdàmú wọn; nitootọ, iwọ kì ibá tí ṣíjú wo ipọnju wọn ni ọjọ́ idamu wọn, bẹẹ ni iwọ kì iba tí gbe ọwọ́ le ohun ìní wọn ni ọjọ idamu wọn. (Esk 35:5,10; 36:2,3.)

14. Bẹẹ ni iwọ ki iba ti duro ni ikorita lati ge awọn ti Juda ti o sálà kuro; bẹẹ ni iwọ ki iba ti fi awọn tirẹ̀ ti o kù ni ọjọ wahala lé wọn lọ́wọ́.

**Idajọ gbogbo awọn orilẹ-èdè.**

15. Nitori ọjọ́ Oluwa kù si dẹ̀dẹ̀ sórí gbogbo awọn orilẹ-èdè keferi: bi iwọ ti ṣe, bẹẹ ni a o si ṣe si ọ: ẹ̀san rẹ yoo si yipada sori ara rẹ. (Esk 30:3; Joel 1:15; Jer 50:29; Hab 2:8; Esk 35:11.)

16. Nitori bi ẹ̀yin ti mu lori òkè mimọ mi, bẹẹ ni gbogbo awọn orilẹèdè keferi yoo maa mu titi, nitootọ, wọn o mu, wọn o si gbémì, wọn o si wà bi ẹni pe wọn kò sí rí. (Jer 49:12,13; 25:15,16.)

**Idande ni Sioni: Ijọba Oluwa.**

17. Ṣugbọn igbala yoo wa lori òkè Sioni, yoo si jẹ mímọ́, awọn ara ile Jakọbu yoo si ni ìní wọn. (Isa 4:2,3; Amos 9:11–15.)

18. Ilé Jakọbu yoo si jẹ iná, ati ilé Josẹfu ọwọ́-iná, ati ilé Esau fun àgékù koríko, wọn o si ràn ninu wọn, wọn o si run wọn; ki yoo sì si ẹni ti yoo kù ni ilé Esau: nitori Oluwa ti wi i. (Isa 40:17; Jer 11:23; Amos 1:8.)

19. Awọn ara gusu yoo ni òkè Esau; awọn ti pẹtẹlẹ yoo si ni awọn ara Filistini: wọn o si ni oko Efraimu, ati oko Samaria: Bẹnjamini yoo sì ni Gileadi. (Amos 9:12; Isa 11:14; Sef 2:7; Jer 31:5; 32:44.)

20 Ati ìgbèkùn ogun yìí, ti awọn ọmọ Israẹli ti o wa laarin awọn ará Kenaani, titi dé Sarefati; ati ìgbèkùn Jerusalẹmu ti o wa ni Sefaradi, yoo ni awọn ilu nla gusu. (1 A.Ọba 17:9; Jer 32:44; 33:13.)

21. Awọn olugbala yoo si goke Sioni wá lati ṣe idajọ òkè Esau; ijọba naa yoo si jẹ ti Oluwa. (Neh 9:27; Psm. 22:28; 67:4; Dan 2:44; Sek 14:9.)